# IROHIN IMOLE

IM LE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No, 724 SATURDAY, JUNE 20, 1964 (2d)


## Awọn Kan Gun Ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre L,ọbẹ

ILESHA:- Ọrọ di pẹntuka nigbati awọn enia kan p rojọ ti nwọ i si jijọ nsọrọ sọ ti ẹnikan sare de lojiji si arin wọn ti o si gun ẹnikan lọbẹ ni ẹgbẹ ni ọjọ Ẹti ti se o o kokandinlogbon Oṣu yi

Ẹniti oran na ṣoju rẹ ṣe alaye fun ori we irohin wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ Afnifẹ re ni o nse ipade kan ti awon oluwarẹ si wa bẹ si arin won igbẹ lafẹ ewe' oko lafẹ ilasa ni awọn enia na ba tuka mọ ara won loju yangan

Ṣugbon nigbati o di ojo keji ni nwon ri oku omo ẹgbẹ Afẹnifẹre ka i ninu awon ti nwon jo se ipade na ninu ogodo kan ti nwon si gun ni; obẹ Irohin fi ṣe wa pe nigbati awon enia na gun lo bẹ tan ti nwon si se akiyesi pe o[illegible] le dide ni won ba gboju si etido kan:

Awon olopa ti gbe omo Afẹnifẹre na lo si Ile-iwosan fun itoju nwon si nse iwadi oro na lọwọ ṣugbon awon omo ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakuko ni Ilesha ti ranṣẹ ṣi olola Azikiwe ati Alhaji Tafawa Balewa lori ọrọ na

Ninu waya na ti awon ọmọ ẹgbẹ mejej ko ranṣẹ' nwon ṣe alaye pe ;;awọn mọ ẹgbẹ Dẹmọ (N. N. D. P.)ni adugbo na ni nwọn siṣẹ na ;Sugban; bi awọn olopa base ti iwad oro na si ẹ o ma gbọ

## Oyinbo Kan "Fẹ D'oju Apapọ Ijọba Bolẹ

# ỌLỌPA MU AWỌN OLORI ẸGBẸ OṢIṢẸ

EKO:— Kẹkẹ pamọ gbogbo enia lẹnu ninu Ile ẹjọ giga kan l'Eko nigbati awọn Ọlọpa mu Oyinbo alawọfunfun kan, VictorLeonard Allen, ( ni ọdun mọkanlelogoji wa siwaju adajọ fun ẹsun pe, o ngbimọ lati gbe ogun ti Apapọ Ijọba labẹlẹ ki o si doju Ijọba bolẹ ni ọjọ ọjọ'Bọ ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o nba Oyinbo alawọ funfun na ṣẹjọ ṣe alaye pe, "ni arin ogunjọ oṣu ti o kọja yi si ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi, ni Oyinbo na da ẹgbẹ kan silẹ larin awọn enia dudu, ti nwọu si npete lati ditẹ si Apapọ Ijọba."



Goodluck

Ọlọpa na tun ṣe alaye siwaju niwaju Adajọ Agba Ile ẹjọ na Ọgbẹni A.R. Bakare pe, "Awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣelu diẹ lọwọ ninu ọran ti o delẹ yi, ṣugbọn awọn onișokoto-penpe ti sọ ẹlẹwu ẹtu rierie nwadi rẹ lọwọ."

Siwaju si i, Ọlọpa na wa rọ ile ẹjọ lati kọ iduro fun Oyinbo na, o si bẹ Ile-ẹjọ pe, ki nwọn jẹki o wa ni iti mọle awọn Ọlọpa fun gbogbo asiko iwadi ọrọ na.

Lẹhinti awọn Ọlọpa ka ẹsun ti nwọn fi kan Oyinbo na tan, ni akọwe Ile ẹjọ na wa bere iọwọ Oyinbo na pe, ṣe o gbọ ohunti nwọn wi ?"

Ṣugbọn lẹsẹkẹsẹni Oyinbo na da akọwe Ile ẹjọ na lohun pe, "Bẹni, gbogbo ohunti ẹ wi ni mo gbọ patapata."

ẸSUN

Lojukanna ni Ọlọpa na kaa si gbogbo Ile ẹjọ leti, ẹsun ti nwọn fi sun pe, "Iwọ Victor Leonald Allen, ko awọn ọmọ ẹgbẹ ọmọ Naijiria kan jọ ni abẹlẹ larin ogunjọ oṣu karun ọdun yi ati ọjọ kẹtadinlogun oṣu ti a wa ninu rẹ yi, lati gbe ogun dide si Apapọ Ijọba Naijiria, ki ẹ si doju Ijọba bolẹ. pẹlu iranlọwọ awọn nkan ija Ogun, nitorina, o ti lẹgbadi Ofin Ijọba eyiti o wa ni oju ewe iwe kẹtalelọgọ'a ninu Iwe Ofin (Page 63 Criminal Code ) awọn arufin,"

Ọlọpa na tun sọ fun Ile ẹjọ pe, "Awọn Aṣiwaju ẹgbẹ awọn Oṣiṣẹ kan ni Naijiria ti nwọn kọ awọn Oṣiṣẹ lati da iṣẹ silẹ laipẹ yi yio farakọrin ninu ọran na ti o delẹ yi."

Lẹhin eyi, ni Ọga awọn Ọlọpanu, wa rọ ile ẹjọ na pe ki o maṣe gba iduro fun Oyinbo na, titi ti awọn yio fi wadi okodoro ọrọ na tan.

Ṣugbọn Adajọ na bere lọwọ Oyinbo na bi o ba fẹ sọ ọrọ kan, Oyinbo na sọ pe, "Ko si ibiti mo le salọ, kini idi rẹ ti ẹ ko fi gba iduro fun mi"

O tun sọ siwaju pe, "Bi ẹ ba gba iduro fun mi, ngo ni aye lati mura silẹ ki n si gba ara mi kalẹ."

Oyinbo na tun ṣe alaye pe, "Bi ẹ ba gba iduro fun mi. ẹ le fi ofin pajawiri gbe mi pe, nko gbọdọ kọja ibiti o ba wu nyin labẹ ofin"

Adajọ: "Nibo ni o ngbe? ṣe ni Naijiria ni?" Oyinbo "Rara o, Naijiria kọ ni mo ngbe"

Adajọ: "Njẹ ti ile ẹjọ ba gba iduro fun ọ, njẹ o ko le sa kura ni Naijiria?"

Oyinbo: "Ibiti ẹ ba fẹ ni ẹ le fi mi si; ṣugbọn ki o mọ jẹ itimọle Ọlọpa."

Adajọ: "Ti mo ba gba iduro fun ọ, nibo ni o fẹ ma a gbe tabi o fẹ ẹ ma a rin kakiri ilu?"

Oyinbo: "Bi mo ba wa ni itimọle, nko ni le ṣe eto fun agbẹjoro."

Adajọ: "Ngbọ, abanirojọ ọrọ na re o, ewo lo wi ṣugbọnnitori iru ẹsun ti nwọn fi kan Oyinbo yi, nko le gba iduro fun un"

Ṣugbọn o ṣe alaye pe on yi ero on pada lọjọ iwaju.

Oyinbo "Njẹ mo le lẹjọ kotẹmilọrun ri lo ipinnu rẹ yi?"

Adajọ II: Bẹni, o ni anfani labẹ ofin lati pe ẹjọ si Ile ẹjọ giga ti o ba fẹ"

Lẹhin eyi ni awọn ọlọpa ba mu Oyinbo na jade ninu Ile ẹjọ, nwọn si lọ fi pamọ si Itimọle awọn Ọlọpa nigbati adajọ yẹ gbigbọ ẹjọ na si ọjọ ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kini oṣu ti mbọ.



Alhaji Adebọla



Ọgbẹni Michael Imoudu

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wa pe, lẹsẹkẹsẹ ti nwon ṣe ẹjọ na tan ni awọn Ọlọpa lọ tu ile Alhaji Adebọla, ati awọn enia diẹ pẹlu rẹ wo ti nwọn si tun lọ si Ile Ọgbẹni Michael Imodu lati fiọrọ wa ọrọ wo lẹnu rẹ

A gbọ wipe, awọn Ọlọba gba iduro awọn enia na, Ṣugbọn on ko mọ bi nwọn ri awọn nkan ti o lodi si Ofin Ijọba nile wọn.

Onirohin wa Ejongboro fi ye wa lana pe, ọlọla Gorming—Brice, Asoju Ijọba Gẹẹsi ni Naijirla yio ṣe eto ki Ijọba le gba iduro fun ọgbẹni Allen ki o si le mọ bi ọgbẹni na fẹ gba Agbẹjọro ati pe boya o fẹ ranṣẹ si awọn enia rẹ nile.

Bi nwọn ba ti pari ẹjọ na si ẹ o, ma a gbọ ninu Iwe rohin wa.

## Wi Ki Ngbọ!

Ọdarun kan ji ọmọ ọdun mẹta gbe ni Shomolu,

Wo oju ewe kẹfa.

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU (Apa 20)

**Lati ọwọ J O Shoyinka**

Ibiti mo ba ọrọ mi de niyi. Nwọn tẹ lee, awọn ejo wọn yi ko yirapada nibiti nwọn fi wọn si lakọkọ. Ayunorunbọ bẹrẹ si tẹ wọn mọlẹ Ṣuasua, nwọn k o gberi, Ogbojuleogun tẹlẹ e ati awọn ẹgbọn rẹ, bẹniẹnwọn ṣe gori awọn ejo yi lai ni ifarapa, nigbati nwọn bọ si ẹhin ilu, Ayunorunbọ pe wọn, o ba wọn sọrọ.



AWORAN YI NI TI AJIRAN ILU AWỌN OKU

Oni „Mo ṣe tan lati ọjọ yi nyọ k i iyin ara rẹ pe ohun dun ọbẹ, mo ṣoju mo ṣẹhin baba nyin.

Lọjọ meje oni ẹiẹti ẹgbọ ẹ o de Ilu Ajiran, jamba kan ko si fun nyin lọna n g o pada nihin, ṣugbọn aki ba mọ ti ẹ b a tun ri idamu ki ẹ ke si mi o.

Ayunọrunbọ pada wa bere lọwọ wọn, o ni nibo ni rẹ ẹgbọn yin Ige ghe wa Ogbojulegun da a lonan pe nigbati awọn ya si ọwọ o si Ige ya s i ọwọ ọtun Ayunorunbọ t u n bere p e, kini ṣe ti ẹko fi ba gba ọwọ ọtun, nwọn ni Eṣu I lu okirioko lo gba wọn ni iyanju pe ọwọ o si ni o dara atipe ko si si iyọnu nibẹ

Ayunorunbọ bẹrẹ s i b a wi oni ẹ y i n alaigbọran ọmọ yi ohunti mo tan yin ẹko gba, mo sọ fun yin p e ki idamu na de bayin kimu ṣe ti ẹko tele rwọn ran Eṣu ni nsọ otitọ fun yin ko s i ilu miran ni n wọn ti yin apadi lo Ẹniti oba si ri ni ọjọ sibẹ ko le lọ mọ nibẹ

Ibẹ ni ina ajoku i n a wa nibẹ ri ẹkon ati ipahirkeke wa oro ina ibẹ ko ṣe fi ẹnu sọ ri oran ibẹko kere.

Ha! o ṣe, o na ṣe nje ibiti gbogbo wahala nyin pari si ni yi? Njẹ Ige nikan ni yio de Ilu Ajiran? Iba jẹ p e ẹ tẹle ọrọ iyanju AGIDI ni, ki bati ri bayi fun nyin. Nba ran nyin lọwọ. Ṣugbọn agbara eṣu poju temi lọ. Angeli Ọlọrun lo le ṣegun rẹ Ige ti de bode ilu Ajiran nisisiyi ngo jiṣẹ nyin fun un, gẹgẹbi enia Ọlọrun yio fi ọ r ọ nyin sinu adura, ko si ohun ti Ọlọrun ṣe ti; Oluwa na ninu rẹ yio gba nyin o digba odi aferi.

O lọ raurau, ọkan ọmọ onilogbo bajẹ, nwọn nsunkun nigbati o ṣe diẹ ogbojuleogun ni oya ki i awọn ma a lọ, nwọn rin irin ajo marun tako nwọn ko ri ẹda alaye kan. Nigbati oku buso kan ki nwọn de Ọrun apadi ni ilẹ ti bẹrẹ si jo nwọn lẹsẹ oru ngmu fi fun atẹgun ina.

Bi nwọn ti ku sata. Ki nwọn de bode Ọrun apadi nwọn ri ọwọ ina ti njo lala la, awọn enia nki-gbe pe oro o! oro o!! oro o!!! ati orugbẹ eyi mu ki awọn ọmọ Onilogbo sa pada ṣugbọn ko boro mọ, ki nwọn to yirapada, Eṣu ti kan wọn lara, oju rẹ pọn bi Ogunna, abọn rẹ paapa da bi ẹjẹ o dudu kirikiri bi dudu ori rẹ da bi ikoko amọ Ogbojuleogun ko mọ ọ mọ, nitori pe o ti parada.

Bi o ti nsọrọ ni ina njade ẹnu rẹ, o ni ẹnyin ọrẹ mi kini ṣe ti ẹko fẹ fi ba wa gbe? Ṣe bi ẹnyin paapa, ti ngbọ ti awọn baba wa, ma npa lowe pe aki jẹ meji ni aba ALADE ẹniti o ba fi isu ko ni mu omi ẹniti o ba mu omi ko ni je isu,

Nigbati ẹwa laiye, ẹti jẹ aiye eti jẹ j... Ẹ nrẹ awọn talaka jẹ e ngba afoju, ẹ ni iya jẹ ọmọ alaini baba fẹ ni alaini se ise ase gbowo titori pe ẹ laṣbara ni ile aiye ọmọ ọba si ni nyin

Awọn talaka ni nwọn wa lọrun rere nisisiyi ẹtọ si ni ki ẹ wa na ẹo si wọọ Awọn Ẹwọn gbangba kan wa li ọwọ rẹ bi o ti fẹ daa si wọn lọruu lati fi wọ wọn sinu ina ni Angẹli Ọlọrun ba fi ija pẹta pẹlu rẹ nitoripe lati igbati Ayunorunbọ ti jiṣẹ fun Ige, ni o fi ngbadun ra si Ọlọrun pe ki o ran Oluranlọwọ si awọn Aburo rẹ Oluwa gbọ adura rẹ, o si ran Angẹli Michael si wọn fun iranlọwọ.

Gẹgẹbi ẹnyin paap ti mọ agbara eṣu, Oba Angẹli Ọlọrun ja to bi wakati kan ki Angẹli to tun ti i sinu ni apada Angẹli na fo lọ awọn ọmọ Onilogbo nwo ko-o- ko-o awọn ko mọ ọna ti nwọn yio gba de ọdọ Ige mọ kan an, ti Ogbojuleogun taju pa ori ọna gbooro kan ni nwọn ba tẹle e bi ere bi awada bi ere bi awada nwọn yọ ṣii afonifoji kan awọn paapa ko ri opin rẹ nibẹ ni nwọn joko si di ọjọ keji.

Ironu wa ba ibeji o su wọn suu nwọn ko mọ bi o ti ṣe pe Angeli-tor pe Ayunọrunbọ ni nwọn mọ Nwọn si nsi yemeji pe Ayuuọrunbọ ko tun le yọ si wọn mọ Sugbọn Ogbojule ogun da ni im ran pe bo mọ ma ku b'Ọmọ ma ye a gbọdọ kọlọmọ ku ewu Ejẹki a pe Ayunọrunbọ fun iran lọwọ ni b ya aje wa ope e o si jade wa

Nwọn sọ ẹdun ọkan wọn fun un o ni ki nwọn di mọ on lapa at'ẹsẹ nwọn di mọ, o lio ba gbe wọn fo afonifoji na da si odi keji koi ti sọ wọn kilarẹ tan ti o fi parẹ mọ wọn loju.

Nwọn bẹrẹ si irin fanji lọ titi nwọn fi yo si Bode.

Ajiran, nigbati ige ri wọn ọkan o sure lọ pade wọn tayọtayọ nwọn bẹrẹ si rohin ohun ti oju nwọn ti ri li ọna o si ti nwọn ya si Mo fẹ ki ẹ mọ daju pe ige ko ri inira kankan li ọna ọtun titi o fi de Bode Ajiran.

Ẹnikẹni to ba de ẹnu bode yi gbọdọ gba to ọjọ meje nibẹ nitori pe oni lati ma wẹ lẹmẹta lojumọ o si ni iwa gbowẹ fun idariji ẹṣẹ ige ti se gbogbo ... koja sugbọn awọn aburo rẹ koi ti see eyi ni o jẹki ige tun duro de ọ ẹ keje miran apapọ ọjọ ti o gbe lẹnu bode wa jẹ ọjọ mẹrinla.

Ẹku irin ẹku wahala de lẹ ku fiti na lala nyin pin loni idẹra de ẹ ma a yo. Ẹgbọn nyin ti sọ ohun ti ẹ wa wa nihin, lọjọ meje oni ti Oluwa ko ba kọṣẹ ẹru rẹ ẹ o foju kan baba nyin inu wọn dun gidigidi, oni bode sisi ilẹ ku fun wọn ni agogo meje irọlẹ Nwọn wole.

Bi nwọn ti wọ. Bode ni agogo meji o si bẹrẹsi pa wọn, nwọn mu ọna ọja pọn, ohun ti o jẹ iyalẹnu ni pe bi ọja yi ti tobi to, ti awọn enia kun inu rẹ to nwọn ko tan ina, gbogbo wọn si wọ aṣọ dudu sagila, eyiti wọn ba fi doju kọ ọja ti nwọn nra nse ni nwọn dẹhin kọ ọ.



# IWE SI OLOTU

## Awẹ Nfẹ Amojuto Ijọba



Ologbe Oloye J. A. Ajao

Olotu mi ọwọn, inu mi dun pupọ lati fọrọ aye ranpẹ ninu iwe Irohin rẹ oloyin mọmọ lati le fi ba awọn ọmọ ilu mi Awẹ sọrọ ati to ati ọrọ iṣiti fun idagbasoke ati ilọsiwaju ilu wa—Awẹ. ■

Mo bẹ ẹnyin agbagba ati ọmọde ilu Awẹ ki ẹ jẹki a ṣowopọ ki a jijọ ja fun alafia ilu wa ki a mura ati sisọ fun awọn nkan idagbasoke ilu wa. Ẹ jẹki awa ọna bi ao ṣe ni ọkan meremere ti ao fitun ilu wa ṣe.

Ilu wa nfẹ ọpọlọpọ atunṣe ejẹki awa nkan ti o jẹ wa niya bi Ina ilẹtriki omi-ẹrọ ati gbogbo nkan ti o fun ilu ni ilọsiwaju ati nnka ọlaju.

Ẹ jọwọ mo bẹ nyin ẹjẹki a pa ọtẹ ti sibẹ kan na, ki asi jijọ sọwọpọ fun ire ati ogo ilu wa, ẹjẹki adi ọkan.

Mo ro pe ti aba ṣe eyi Ijọba yio tete fun wa ni awọn nkan ti o jẹ wa ni iya.

Lakotan ọrọ mi mo kesi awọn ilu Awẹ pe ọrọ na di ọwọ nyin o ẹba wa tun ilu wa ṣe ẹnu ni aberẹ fi tun aṣọ rẹ ṣe.

Emi ni
Turde Oladipupọ

AWẸ

## Kogberegbe Nkọ

Olotu,

Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le fun mi ni aye diẹ yi lati fi bere ohun ti ode si Woli Kogberegbe ti a ko fi gburo rẹ ninu iwe nyin mọ tabi o ti lọ si Jerusalem ni.

A fẹ mọ bo ya Ko si nile, ni tabi Olotu ni ko fẹ ọrọ rẹ jade, ẹsọ fun wa ki a gbọ.

Ti o ba si ṣe pe o rẹ Woli ma yi ni ki o jọwọ ki o maṣe jẹki o rẹ ẹ, nitori lati ọjọ ti ako ti gburo Woli Kogberegbe mọ ni aipin rẹ bi yun wa.

Ẹ ba wa, wa Kogberegbe lọ.

Emi ni
Iyaafin Jenet
Jokotade

AGEGE.

## Ẹ kilọ Fun Ẹyọ

Nba sọpe bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin Oloyin mọmọ ti ijade lojojumọ lati kesi Ijọba Ibilẹ Eko ati alaiyeluwa Ọba Adeniji Adele ti ilu Eko pe ki nwọn ran wa lọwọ lati kilọ fun awọn Ẹyọ ki nwọn mọ ma fi iya jẹ enia ma ni asiko Ẹyọ Iya ti nwọn fi njẹ enia ti pọ ju.

Eyiti o buru nibẹ ni nina ti nwọn ma na ni kẹkẹ ni a na ṣubululẹ, kaka ki nwọn daro rẹ nwọn atun ko ọpa abata bo, ẹlomiran nju kẹkẹ ologere rẹ silẹ nigbati iya ba pọju.

Onun ti ofin sọ nipe, ẹniti o ba bọ bata olokun nwọn ngo gbọdọ na sugbọn ati enia bọ bata olokun tabi abọyọ gbogbo wọn ni ẹyọ nna ni a na da'pa si lara

Ofin tun sọ pe nwọn ko gbọdọ na ẹniti nwọn ko ba mọ ati ẹniti nwọn mọ o ati ẹniti nwọn ko mọ nina ni awọn Ẹyọ yi nna gbogbo wọn.

Ọpọlọpọ ni o si nmọ ara bi alabiyamọ ti nwọn tun fi owo ra ipara oyinbo ti o njẹ so ro nitorina mo bẹ awọn Ọlọfa wa, awọn bi Oloye J. M. Johnson, Adajọ Agbabu ki nwọn ran are lọwọ lati kilọ fun awọn Ẹyọ wonyi n gba miran lati mọ tẹle ofin.

Ẹku iṣẹ olotu

Emi ni
J. A. Amosi

EKO


BI O BA NI

**Iwe—Titẹ**

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyawo**

TE TE KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ko si ri iyatọ*



**Ibanujẹ Tabi Ironu Rẹ de Opin Ayọ De**

Ojulowo Egbogi awọn Faranse gidi ti a npe ni

**'CORSIVER'S**



Ojulowo ati Ajẹbidan Atamatase Egbogi ti a ṣe ni pataki Fun „ARỌN KINIṢA" tabi LATANATAN, ti o ma mu idiwọ wa fun Obinrin lati Fẹraku tabi lati ma ṣe abiyamọ meji rẹ kosi kakiri igboro ilu Eko. Lẹhin ti o ba ti lo egbogi arọn yi tan ti inu-riru, aya ririn, ẹhin didun tabi aikoto ẹjẹ lara, ẹjẹ dudu ibadi gige tabi sisan ba nyọ ọ lẹnu sibẹsibẹ bere ojulowo egbogi ti awọn Oyinbo ṣe nipataki fun AJO "OBINRIN" ti awọn amodi wọnyi ba nyọ lẹnu ti wọn npe ni egbogi na njẹ ni ṣọbu awọn

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos
Waterloo Stores
8, Palm Church Street, Lagos,
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji Lagos.)
ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos
ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:—
IṢẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌ


**Ẹ ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu**

# Imọlẹ Ko Dara

## Lati Ọwọ :— Bọsẹde Shoyinka

ANSAR—UD—DEEN SCHOOL, ITIRẸ.

Ẹ ku owurọ o
Ẹnyin ọmọ ile iwe
Ẹlẹgbẹ mi
L'ọkunrin ati l'obinrin
Imọran mi oni
Duro lori
Imọlẹ ko dara
Ti ẹ ba ji
Ni owurọ
Ẹ ran awọn obi nyin lọwọ
Nipa titọju ile
Ti ẹ ba si de
Ile Iwe
Ẹ tẹti silẹ
Si ẹkọ
T'awọn olukọ nyin
Ba nkọ nyin

Ẹ maşe jẹki
Ere gba nyin l'ọkan
Laseko ẹkọ
Toripe ọmọ ti ko
F'ọkan s'ẹkọ rẹ
Yio d'akurẹtẹ l'ọla
Ti awọn Olukọ nyin
Ba fun nyin
Ni'şẹ ile şe
Ẹ şee tọkantọkan
'Toripe ọmọ ti yio
Jọ aşamu
Lati kekere
Ni i ti şẹnu
Şamuşamu lọ
Ẹ tẹti ẹ gbọ o.
Imọlẹ ko dara.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Amodi leşe ọ loni, şọra ki o maşe sọrọ kọrọ, sọ ohunti o nti ẹnu rẹ jade si awọn obinrin, iwọ yio padanu owo, aşọ fun jaroba mọto, Bi nwọn ba pe ọ sibi ase kan kọ silẹ maşe iọ,

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Ohun t i o njiro loni dara jọjọ ki o si fi han awọn to fẹran rẹ, maşe lọ sibi ere pupọ, şọra, maşe fi ọgbọn ati lakaye ti o şe jamba fun ẹlomiran.

ARIES (Mar 21 - APRIL 20) Şọra ki o si şakiyesi awọn ọrọ ti o ma nsọ jade, ki nwọn ma ba pe ọ lati tunba rẹ şe pẹlẹpẹlẹ loni

TAURUS (Apr 21 May 20) Awọn kan le gbe ija ko ọ loni ninu ile rẹ maşe ba ẹnikan gbonu bẹni ki o maşe la ki o ma ba di ogun ẹjẹ.

GEMINI (May 21 - June 21) Gbidanwo lati ba obinrin sọrọ ifẹ loni gẹgẹbi o ti wa lọkan rẹ lati şe tẹlẹ

CANCER (June 22 - July 23) Ẹnikan nwa oju rere rẹ lowọlọwọ. ninu ilẹ ebi rẹ, iwọ gbagbe ti ana rẹ lati gbọ ti ẹni ẹlẹni, ọpọ enia yio ma şe aniyan pe bawo ni iwọ ti ni suru to, tọju ara rẹ, ki o si şe jẹjẹ.

LEO (July 24 Aug 22) Afojudi rẹ yio ko ipanujẹ waba ọ loni igbagbe ti o ma ngbagbe ọrọ, yio jẹki nkan nlọ fo ọ da, Bi o ba le şe jẹjẹ, inu rẹ yio dun ki o to sun li ale yi.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Şe bi ọkunrin ki o si tọju işẹ rẹ, bi bẹkọ iwọ yio gbọ irohin ti ko dun mọ ọ ninu Maşe jẹki inu rẹ bajẹ loni rara.

LIBRA (Sept 24-Oct 24) Maşe ba ẹnikẹni se gbolo hun aşọ, ma si ja, jẹjẹ ni ki o şe jalẹ ọjọ oni,

SCORPIO (Oct 25-Nov 22) Mase işẹ pakanike kan loni, jẹjẹ ni kio ma se jalẹ ọjọ oni maşe ro ohun kan tabi ki o gbe ironu kan si aiya

SAGITTARIUS (Nov 23- Dec 22) Ilera ara rẹ, yio jẹki ọgbọn orirẹ peye orire ati igba rẹ mbọ wa tan imọlẹ rẹ si ọ lara lairo tẹlẹ.

CAPRICORN (Dec 23 - Jan 21) Owurọ yi yio dara fun ọ, gbogbo ọrọ rẹ yio gun regerege

MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS *Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DILIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbse Street,**

Phone 21985, Lagos.

## Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu sise iwosan ati egbogi ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ko ni yọọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ọ ohunkohun ti oba si dawọle rere ni yio ja şi awọn babalawo ti o ngbowo gba aşọ lọwọ enia ko ni ri ọ mọ, iye owo 20/-

Iwẹ egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko şe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ şaşa ni arun ti o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arunkarun tabi asasi kan le pa ọ mọ. Iye owo 25/-

Turari Ẹyọnu Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti şe şalaye rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwọ ko ni mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo yio si wa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/- |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ile Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọşẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6d |
| Lilo ati agbara Psalm Işẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu turari | 30/- |

## APEJUWE ILE IŞẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni ile itawe wa wa, Ti o ba fẹ fi owo ranşẹ fun ọja rẹ. Adirẹsi mi niyi:—

**J. O. Shoyinka**
c/o Postal Agent
1, Isiba Street,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba.

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni gareji Iddo, Mushin, Ikorodu road ati ni gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba rii ra wa si ọdọ mi ngo ta fun ọ.

OKPARA SỌ PE:

# Abamọ Ni Ajumọṣepọ Ẹgbẹ N.C.N.C. ati N.P,C,

AJEGUNLẸ:—Olotu ipinlẹ ila orun Naijira ati olori ẹgbẹ Alakukọ Dokita Micheal Okpara sọ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ keje oṣu yi pe ẹgbẹ on N. C. N. C. ṣe asiṣe ọdun 1959 nigbati nwọn ba ẹgbẹ N P C ṣe ajumọ ṣepo ti igbimọ asofin ijọba apapọ



Oloye M.I. Okpara

Dokita Okpara si sọ pe nwọn ko ni se iru nkan bẹ mọ ati pe ajumọṣepọ yio dopin ninu ọdun yi.

Olotu na nba awọn enia sọrọ ni Ajegunlẹ fun opin irin ajo rẹ si ipinlẹ iwọ Orun Naijiria ninu awọn akiyesi ti olotu ipinlẹ ila orun ṣe, o si sọ pe ẹgbẹ Dẹmọ N N D P si jẹ Ọmọ N P C ti nwọn da silẹ ni Ipinlẹ iwọ Orun lati di Ọmọ Afọnja keji nigba ti awọn Eleyi si njẹ imọ inu ẹgbẹ N P C lati wa fi ẹsẹ mulẹ ni ipinlẹ iwọ orun ati ila Orun ẹgbẹ NNDP.

Dokita Okpara si tun sọ pe ẹmi oṣelu wa ninu awọn enia ipinlẹ Iwọ orun ati pe nwọn si ti duro ṣinṣin lati gbogun ti eto efin to jẹ ti wọn.

Olotu ila Orun si tun sọ pe o si ti pin awọn ara ipin lẹ na l'ẹmi lati tele awọn oṣelu to nyi pada bi ọga ni ipinlẹ iwọ Orun

Nwọn si tun fẹ ki wọn tu ile igbimọ aṣofin ipinlẹ iwọ Orun. Olotu na si tun sọ pe awọn enia ipinlẹ iwọ Orun ko fẹ iyasọtọ ni ilẹ Naijiria.

IBA'WI

Dokita Okpara si bu ẹnu atẹ lu awọn olori ẹgbẹ N N D P nipa iwa wọn bi nwọn ti fẹ ma ṣe iyatọ orilẹ kan ni Naijiria ki nwọn le bori lọna kọna.

Olori ẹgbẹ N C N C si tun sọ ninu ọrọ pe ẹgbẹ on N C N C ati ẹgbẹ Afẹnifẹre yio bori ninu ajumọṣepọ wọn lasiko idibo si ile igbimọ apapọ le fi ijọba rere mulẹ ni ilẹ Naijiria

Dokita Okpara si tun ba ẹgbẹ N P C wi gegebi nwọn ṣe fẹ gba rogbodiyan ti awọn oṣiṣẹ to da iṣẹ silẹ si ọrọ ti oṣelu, Olotu na si tun sọ pe ko si itẹlọrun fun ilẹ Naijiria nipa gbogbo nkan to nṣẹle ni ilẹ Naijiria bayi ati pe awọn to si wa gegebi Olori ko si ni ọgbọn

Dokita Okpara si tun sọ pe o jẹ alairori fun olori ijọba kan ki o wa ni isimi nigbati orilẹ rẹ si wa ninu ewu bayi.



Alhaji Ahmadu Bello



# Iwọ Ha Fẹ Kọ le Bi ?

Bi o ba fẹ ra ilẹ tabi o fẹ ta ilẹ tabi boya o fẹ kọ ile,

Tete kọwe si wa fun gbogbo awọn ohun ti o ba nfẹ.

Bi o ba kọ ile, a le ma a ba ọ gba owo lọwọ awọn olugbe ile rẹ kia kia, ki owo na a si tẹ ọ lọwọ ni asiko

Tabi ti enia ba je o lowo ti ko san, kọwe si wa, were ni a o ba ọgba a lọwọ rẹ

Fun ẹkunrẹrẹ alaye, kọwe siwa, ki o si dan wa wo lẹ e kan ṣo ṣo a o si fi ohun gbogbo tẹ ọ lọrun

J.O. Shoyinka.
General Manager
1, Ishiba Street
Itirẹ—Yaba

AWỌNEGBOGI ATỌMATASE PATAKI TI ODAJU LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU AKUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU EKINI:-

## SEDO — PAYAL



(IPARA BI ORI)

Je ojulowo egbogi lati fi se itọsan orisirisi arun awọ "ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara gegebi owọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi didun nigbakugba Inarun tabi ako Inarun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela lapa lapa Ara sisu Alefo Ekusa lori ọmode tabi agbalagba egbo ẹsẹ tabi Adaajina egbo ẹsẹ ati orisirisi awọn amodi tabi awọn arun ara omiran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI

Dara pupọ julo fun awọn ti amodi ti a daruko wọn si oke iwe yi ba nyọ lenu nitoripe iṣẹ rẹ ni lati ma mu gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "EJẸ ARA" enia, san patapata a si ma ṣe iṣẹ ribiribi ninu "oju" enia pẹlu. Awọn ti oju wọn a ma "nsu" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o dibi enipe nkaakan wa afara si o u wọn yio bere si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyanju lati ma lo egbogi Jamani yi de de fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbọuṣẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbọnṣẹ dede lojojumọ tabi ti igbọnṣẹ wọn mn nle korokoro nipa bayi jedijedi a berẹ si ma yọ wọn lenu beni o si dara fun lilo fun awọn onijedijedi pẹlu awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri Ṣọbu ilu Eko ati igberiko Bere wọn ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo (P. A. T.) Medicine Stores
8 Palmchurch Street Itafaji Lagos
NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.
Adedun Chemist 4 WakewaStree Yaqa


## Ẹ ma a Ka we Irohin Imọlẹ Lojojumọ Ki ẹ si maa Polowo Ọja Nyin Sinu Rẹ Pẹlu

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 724 SATURDAY JUNE 20, 1964 (2D)


## Ọdaran Kan Fẹ Pa Alakoso Ijọba

ANKARA:- Adajọ Ile ẹjọ giga ilu Ankara ti se idajọ pe ki ọdaran kan, Mesut Suna, ẹni ọdun mejidinlogun lọ si ẹwọn ogun ọdun, nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa fi kan an pe ofẹ pa alakoso ijọba Ankara Ọgbẹni Inonu.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye pe, ni ọjọ kẹtalelogun oṣu keji ọdun yi, ni ọgbẹni Mọmu wọ moto rẹ ti o si sare lọ si ile igbimọ Asofin lati lọ ṣe ipade. Ṣugbọn ọdaran na lọ lugọ sinu igbo kan, bi mọto na ti de ọdọ rẹ ni o ba yinbọn ilewo ti o wa lọwọ rẹ ni igba mẹta ṣugbọn ko si eyi ti o ba Alakoso ijọba na ninu mẹtẹta

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn ọlọpa ti o wa ninu mọto na lai duro, nwọn si mu ọdaran na lọ si Tesan awọn ọlọpa. Ọdaran na ko tilẹ tiju ti o fi nsọ niwaju adajọ pe ni tootọ ni on fẹ Alakoso ijọba nitoripe on lero pe on nla ọ o si iku ti o pa ẹniti o ti wa ni aye na ki on na to debẹ.

Ni adajọ ba ni ki ọdaran na lọ si ẹwọn ogun ọdun fun ẹṣẹ igbidanwo lati pania, ki o si lọ fi ọdun mẹjọ (8) taman ... ọtu ... ripe ... j ... bo ... t o ... gbe ... ri ... arin ilu tabi ki ... tun ṣe wọn oṣu mẹfa kun ọdun mẹjọ

# MAKANIKI KAN JI ỌMỌ ỌDUN MẸTA GBE!

IKẸJA:— Gbẹgẹdẹ"gbina ninu Ile ẹjọ ganran Ikẹja ni ana nigbati awọn ọlọpa mu ọdaran ajọmọgbe kan, Matth Olusanjọ, ẹni ọdun mọkandinlogun ti o nkọ iṣẹ mọkaniki wa siwaju adajọ fun ẹsun ajọmọgbe

Ọlọpa ti o ba Ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, Ọdaran na wo inu ile kan lọ ni Shojuolu, o si bẹrẹ gbe ọmọ kan, Kasimawo Adebayọ ẹni ọdun mẹta gbe nigbati iya ọmọ na lọ si Ṣọọṣi ti o si fi ọmọ na sọ ẹni kan nile ni alẹ ọjọ na.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe bi ẹniti nwọn fi ọmọ na sọ ti ṣe wọ ile idana lọ lati lọ gbe ọbẹ kana, ni o ba gbọ ohun ọmọ na ti o nsọkun ninu iyara, bi o si ti sare jade, ni o ba pade ọdaran na ti o gbe ọmọ na kọ ejika ni o ba fi ariwo ta.

RAGABU

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ara adugbo ba sare jade ninu ile, ti nwọn ragabu ọdaran na ki o to mu mọ wọn loju.

Nigbati nwọn mu ọdaran na ni nwọn ba mu lọ si Teşan awọn Ọlọpa Ṣhomolu ki awọn Ọlọpa tomu ọdaran na wa si kotu.

Ninu ẹjọ ti Ọdaran na ro lati fi gba ara rẹ silẹ, o ṣe alaye pe, itọ lo ngbọn on ti on si tọrọ aye lọdọ ọkunrin papa kan ti o duro niwaju ile na pe on fẹ tọ ti o si fun on laye ki on to sare wọ inu ẹhinkunle ile na lọ.

Ṣugbọn b i cn t i ṣe ntọ lọwọ ni on kan ni ẹnikan ti o ragabu on latii ẹ h i n wa ti itọ t i on fẹ tọ si da mọ on nidi wa! ! i t ọ na si salọ!!

Ọdaran sọ pe itọ ni on lọ tọ ninu ile n a ki i ṣ e ọmọlọmọ ni on lọ gbe bi awọn obi ọ m ọ mu a t i awọn ọlọpa ti ṣe wi fun ile ẹjọ ninu ẹjọ wọn

Nigbati adajọ Agba Ile ẹjọ na, Ọgbeni Kesia gbẹ ẹjọ tọ tun tosi ni o wa yọ ọjọ idajọ rẹ si ọjọ Abamẹta ti ise ọjọ kọkanla oṣu yi.

Bi nwọn ba ti ṣe ẹjọ na si ẹo ma gb ọ ninu iwe Irohin wa!

## ỌLOYE GBENLE ṢI ILE TITUN

MUSHIN:— Ọjọ pataki ni ọjọ isinmi ti ṣe ọjọ kẹrinla oṣu kẹfa ọdun yi jẹ fun gbogbo idile Phillips Gbenle fun ariya pataki ti nwọn ṣe fun ti ile ṣiṣi ni No 64. Railway Line, Mushin.



OLOYE PHILLIPS GBENLE

Lẹhin adura fun iṣile na nwọn ko gbogbo ere ariya to ku na wa si ile rẹ to ngbe ni No 25, Iṣaga Road Surulere. Ariya ọjọ yi pọ tobẹ gẹ ti gbogbo awọn ẹbi Gbenle na fi Oye da Phillips Gbenle na ni ọla ni ọjọ yi loju gbogbo awọn enia l'ọkunrin ati l'obinrin to wa sibi ere ariya ile ṣiṣi na

Oye ti nwọn fun ni ọjọ yi ni "OLORI" GBOGBO ẸBI GBENLE. Nwọn si mu Phillips Gbenle wa siwa ju awọn alagba wipe, loni ti ṣe 14: 6: 64 awọn fi P h i l i i p s G b ẹ n l e jẹ olori awọn, awọn si nfẹ ki awọn ọlọpa na b a awọn fun ni adura. Gbogbo awọn agbagba n a si ṣ e adura.

Lati gbogbo ijoko ọ j ọ na si dun tobẹ ti ọpọlọpọ awọn to jẹ ẹgbẹ rẹ ... pe 'C h i e f Gbenle", "Chief Gbnle", Ọlọrun yio jẹ ki ire ile ṣiṣi bayi kari gbogbo awọn ọmọ Ijọmu, Oro, Amin.

Awọn enia pataki pataki to wa sibi ere ariya ile ṣiṣẹ na ni, awọn bi ọ g b ẹ n i ọ l ọl a Ọlọla Joel Gbadeyan a l a g a Ijọ Anglican Church. Ijọmu ẹka ti Eko Awodele Ẹlemọṣhọ; Ọlọla R. O Aji obi, Paul Ọdẹwọle Olori ẹgbẹ Imọlẹtan Ben Gbadeyan, George Ibiọẹye, Iya afin Madam Fọlọrunṣọ Akoṣile, Madam Felicia.

Adeduntan, Abibatu Foyekẹ, Awawu, Abikẹ, Famyun Onibiyọ Barikisu Ajọkẹ, ati ọpọlọpọ awọn ti ako ri aye lati darukọ.

Ọmọ Ijọmu ọrọ kan la wa lati pe, Oloye Ọbanle Kanna yini awọn ọmọ Ijọmu ti orukọ ẹgbẹ wọn njẹ Ẹgbẹ ọmọ owọ Jesu kọkọ li jẹ Oye Babo Ẹgbẹ wọn fati nkan bi Ọdun mẹrin sẹhin Iwa rere ni esọ enia

Awa oniwe ronin Imọlẹ ki Gbogbo ẹyin ẹbi Oloye Gbenle' oye amọrio lie na yio tura o.


Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 20/6/64